# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,492, TUESDAY OCTOBER 26 1965 (2D)


## Ijẹsha Da Ẹgbẹrun Apoti Redio Pada Fun Ijoba

ILESHA:- Gbogbo enia ti o wa ni Ilesha ati agbegbe rẹ ni o ti fi aifọkan tan ọrọ to njade lati inu ẹrọ asọrẹ magbesi ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lori bi o ti npolowo fun ẹgbẹ Dẹmọ lojojumọ papa lori ibo ti Ipinlẹ na di ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi eyiti gbogbo ọrọ ti njade ninu apoti Redio na ko ba eti mu rara.

O le ni ẹgbẹrun enia to gba apoti na silẹ ti nwọn si ti fi ibinu da apoti na pada lori isọkusọ ti nwọn ngbọ lati inu rẹ, ẹlomiran ti apoti tirẹ pa patapata ti nwọn ni bi o ba ya awọn ti ngba owo lori apoti Redio yio wa gbe nkan wọn. Ẹlomiran tilẹ gbe tirẹ sita ki o le ya wọn lati gbe nkan wọn lọ.

Gegẹbi ifọrọwe ọrọ ti asoju wa to wa ni Ilesha ba awọn enia na sọ ni o ti ṣe alaye fun oniwe irohin pe ọrọ ti awọn ngbọ ninu apoti na ti ba nkan ti awọn nfe jẹ, ki iṣe ohunti awọn nreti ni o njade nibẹ, paapa bi o ti nka awọn enia to wọle ninu ibo ti nwọn di lọ yi ko tọna rara, ti ẹgbẹ Dẹmọ ni Redio na nṣe

Ati pe bi o ti ku nkan bi ọsẹ diẹ ti nwọn yio dibo ni awọn ngbọ pe, nwọn fẹ pa Redio na pọ mọ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun eyiti o jẹ iṣẹ tirẹ lati ma bu ẹgbẹ UPGA ki o si ma yin ẹgbẹ Dẹmọ

Bi a ti gbo pe nwọn ko papọ mọ ti Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun mọ inu wa yio dun pupọ, ṣugbọn bi o ti si wa lọna yi, ko si ohunti a le ṣe ju pe ki a yara tete da apoti Redio na pada fun wọn lọ.

# AWỌN YORUBA DAHO-MEY BA ADEGBENRO YỌ

AJAṢẸ-DAHOMEY:— 'Irohin ko to afọ,uba, ẹni ti o ba de bẹ lole so ni Irohin ayọ nla to gbojikan lario ilu Ajaṣẹ, nibẹ Dahomey ni ọjọ ti nwọn gbọ ọ ninu Ẹrọ-asọrọmagbesi (Radio) wipe Adajọ ti da Alhaji Adegbenro Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre pẹlu gbogbo awọn ẹmẹwa rẹ silẹ, lori ẹsun ti nwọn fi kan wọn lori orọ idibo ti nwọn di koja sẹhin ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria laipẹ yi.

Onirohin wa to lo si irin ajo rẹ lati Eko lọ si Lome laipẹ yi fi nye wa wipe, lati ọjọ ti ike de abayọri ibo ti nwọn di ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ti jade, ni tọmọde-tagba ọmọ Yoruba to mbẹ ni ilu Ajaṣẹ titi lọ de Cotonue ti kun fun ibanujẹ, Bi abayọri ibo na ti jẹ ohun ẹdun ọkan wọn to, kosi adugbo kan ti enia ma de ninu ilu na ti ko ni ri to enia meji tabi mẹta ti nwọn yio duro, ti ko ni jẹ pe ọrọ idibo yi ni nwọn nsọ.

Pataki, ohun to wa jẹ ohun ẹdun ọkan won ju'ọ ninu ọrọ na ni, mimu ti nwọn tun gbọ wipe, nwọn tun mu Alhaji Adegbenro pẹlu diẹ ninu awọn Ogunnagbongbo.

Ọmọ ẹgbe rẹ, ṣugbọn nigbati nwọn tun gbọọ ninu Radio wọn pe, adajọ ti da Alhaji Adegbenro pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ silẹ ni alaikofi iya jẹ wọn ni gbogbo ilu Ajaṣẹ titi lọ de Cotonue ti gbojikan fun ayọ nla.

Ọkan ninu awọn ọmọ Yoruba ilu Ajaṣẹ sọ fun onirohin wa pe titi ti nwọn fi Alhaji Adegbenro pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ sile lo dara pupọ ati pe, o to ohun idupẹ, gẹgẹbi owe awọn baba wa kan to sọ pe "Ohun to nfẹ sọ ni di ẹru, to ba ṣeni ni iwọfa, o yẹ ki a ma a dupẹ"



**Alhaji D. S. Adegbenro**

Adele Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ

### ILU LOME

Onirohin wa fi ṣnye wa pe ki nwọn to mu Alhaji Adegbenro pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ ni on ti koja si Lome nilẹ Togo, o ni, nigbati on wọ inu ilu na, o, ni bi ọmọ Yoruba ti pọ ninu ilu na to, o ni nwọn ko sọrọ meji to ju ọrọ abayọri ibo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti nwọn di kọja lọ laipẹ yi, o ni pẹlu ẹdun ọkan ni olukuluku wọn fi sọ ibiti ibo na yọri si.

Oni ohin wa fi nhan wa wipe, nigbati on ri gẹgẹbi ọrọ idibo na ti ṣe jẹ ohun ẹdun ọkan wọn, on fi ẹgbọn wadi lọwọ ọkan ninu awọn ọmọ Yoruba to mbẹ ninu ilu na wipe Kini ṣe ti ọrọ abayọri Ibo ti nwọn di ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria laipẹ yi ṣe jẹ ohun ibanujẹ fun gbogbo enyin ọmọ Yoruba to mbẹ ni Lome nigbati ki ṣe wipe nilẹ Naijiria ni ẹ wa?

O ni, ki ẹniti on ba bere ọrọ lọwọ rẹ to ba si da on lohun, o kọko bere wipe Burọda! Ẹgbẹ Oṣelu wo ni iwọ nṣe? Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni, tabi Ẹgbẹ Dọmọ?

O ni, nigbati on nfẹ, wa awawi o ni kiakia ni ọkunrin na ti sọ fun on wipe, Bi o ba ṣe ẹgbẹ Dẹmọni ni o, nase jafara lati kuro ninu ilu Lome yi loni, nitori pe, bi awọn ọmo Yoruba to mbẹ nihin ba mọ pe ọmọ ẹgbẹ D ẹ m ọ ni ọ ọpa kan ni nwọn o fi ti ọ jade.

Onirohin wa fi nye wa wipe pẹlu ibẹru bojo ni on fi nsọ fun ọkunrin na wipe Emi ki iṣe ọmọ ẹgbẹ Dẹ—mọ, omo ẹgbẹ Afẹnifẹre ni mi ati pe mo wa wo ọrẹ mi kan nihin ni.

### FIRIAONA IBADAN

Onirohin wa nsọ fun wa wipe lẹhin ti on sọ fun Ọdọmọkunrin na bẹ tan, ni o wa fi ye on wipe, ọpọlọpọ ni Ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre to mbẹ inu ilu Lome yi, o ni; bi awọn ọmọ Yoruba ti pọ to ninu ilu yi, o fẹrẹ to ida mẹta wa ni ẹgbẹ Dẹmọ ti fi owo-ori le jade kuro ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, A si ti pinnu wipe bi ẹgbẹ Afẹnifẹre' tabi ẹgbẹ Alakukọ ti nwọn npe ni UPGA ba tigba Ijọba na ninu ibo ti nwọn di kọja yi lọwọ ẹgbẹ Dẹmọ ni awọn yio pada sile, ṣugbọn, nigbati a gbọ abayọri ibo na o jẹ ohun ibanujẹ fun gbogbo ọmọ Yoruba to mbẹ nihin, a si ti pinnu wipe, bi o ṣe ogun ọdun ni ẹgbẹ Afẹnifẹre to le gba Ijọba na pada kuro lọ wọ "F I R I A ONA" Ibadan ni a o to pada silẹ

# Iwe si Olotu Irohin Imolẹ

## A Nreti Ipadabo Awolowo

Olotu, Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba ni aye diẹ ninu iwe nyin t o kun fun ọgbọn ati oye lati kesi awọn Olori Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria yala ẹgbẹ Afenifẹre, Alakukọ ati ẹgbẹ Dẹmọ lati yara tun Ipinlẹ wọn ṣe lori rogbodiyan to nṣelẹ lojojumọ ni Ipinlẹ ni ati pe ohunti rudurudu to nṣelẹ na le fi pari ni ọna bi nwọn yio ṣe, ṣe etu bi Olori Ipinlẹ Iwọ Orun eyiti Olorun ti yan si awa Yoruba ti iṣe Oloye Ọbafẹmi ‡Aw olọwọ yio ṣe jade lọgba ẹwọn

O yẹ ki ẹnyin ti ẹ jẹ Olori ẹgbẹ Oṣelu Ọba ati Ijoye Ipinlẹ I w ọ Orun lọ ronu si eyi pe, Ninu awọn enia pataki mẹta to ja fun Ominira ilẹ wa ni Oloye Awolọwọ Dokita Azikiwe ati Alhaji Ahmadu Bello.

Ṣugbọn ẹ jẹki a fi oju inu wo awọn enia na ki a si wo iru ipo ti nwọn wa ni Ipinlẹ Olukuluku eyiti iṣe Ila Orun, Ariwa ati Iwọ Orun ki a to ya Ipinlẹ Agbedemeji I w ọ Orun kuro. Bẹẹni awọn enia mẹta yi ni a mọ gẹgẹbi Olori ni Ipinlẹ wọn.



Oloye Ọbafẹmi Awolowo

Nitori e y i ẹ lọ r o n u ẹnyin Yoruba ki ẹ maṣe fi enia ti wa sinu Okunkun lẹhin ti o ti ja fun wa ti a ti ṣẹgun. Mo fẹ ki ẹ lọ mọ daju pe bi O l o y e Awolọwọ ko bi jade ko le si irorun ni Ipinlẹ wa rara Eleyi di ọwọ ẹnyin Olori ilẹ wa.

Olotu abọ mi re O, ẹ ṣe pupọ fun aye ti e gba mi ajinde yi ma jẹ fun nyin O.

Emi ni
Ṣina Adesanya

EKO.

iwọ orun Naijiria pe ki nwọn ran awa enia ilu Bariga lọwọ ki a si ma ri omi na mu ati pe omi kanga ti a ma ngmu ni ilu Bariga yi si nko aisan ba opolopo awọn omodẹ ti ko ti ni agba ra to ti o si tun jẹ pe aisan lọ si nfa si ara awọn ọmọ Ini awa enia ilu na yio dun bi Ijọba Ipinle Iwo—Orun Naijiria ba le fun awa enia ilu Bariga ni awọn ohunti a bere yi ninu awọn nkan ti a tun nbere ni ile Iwosan ati ọja nla eyiti awọn Obinrin ilu na yio ma na gegebi ti ilu miron.

Olotu mo dupe fun aye ti e gba mi ọkọ ọba ko ni sa nyin lese

Emi Ni
J Avọ Abiọdun

BARIGA

## A Dupẹ O

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni ayẹ diẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati dupẹ lọwọ awọn lẹgbẹlẹgbẹ ti nwọn ba wa ta Card awọn ẹgbẹ bi ọrẹ marun, ẹgbẹ amuludun ọrẹ mẹwa ẹgbẹ ọrẹ mẹsan ati awọn ẹgbẹ to ku ti aye ko si lati darukọ wọn.

Bakanna ni mo tun dupẹ lọwọ awọn iyawo egbe ore mẹta gegebi nwọn ti ṣe nu asọ fun ti ajọdun, Bi mo si tun ṣe ni ikilọ fun nyin ki e se iranti ire iwa ti o yọ awọn kan l'ẹgbe ninu ara nyin eleyi ni lati ko nyin loghon.

Mo si be enyin egbe ore meta jakejado ile Naijiria ki e tele ofin egbe wa dada nitoripe eniti o ba ṣe ori kunkun fun egbe ao se eto fun oluwarẹ

Mo ki alaga egbe na Ọgbẹni Y Amuda Giwa Oluwa ko ni gba lakaye rẹ ti o fi se eto egbe na mo si ki bogbo egbe l'agba.

Olotu mo dupe pupo fun aye ti e gba mi oko oba ko ni sa nyin lese o

Emi ni
R A Bakare

## Bariga Nfẹ Omi-Ẹro

Olotu inu yio dun bi ẹba le gba mi ni aye diẹ ni nu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati kesi Ijoba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijira lati ṣe iranlọwọ fun awa olugbe ilu Bariga ati agbe gbe rẹ lati fun wa ni erọ omi eyiti yio si je irorun fun awa enia ilu na lati le ma ri lo gegebi ti awon ilu miran ni Iwo Orun Naijira

Mo ro pe o ti to ọdun di ẹ sẹhin ti a ti nkesi Ipinlẹ EKO

## Iwo Ha Nfẹ Ile 'Eko Bi ?

| | |
|---|---|
| Room | £3 |
| Room | £4 |
| Room | £5 |
| Room / Parlour | £6 |
| Room / Shop | £15 |
| Flat (Lagos) | £20 |
| Flat (E.B) | £25 |

Ti o ba nfẹ ọkan ninu awọn ile wọnyi yara tete lo r Ọgbẹni ODUS:— 187, Bamgboṣe Street Lagos. ni deede agogo mẹrin irọlẹ si agogo mẹfa irọlẹ. ijafara lewu anfani nla kan ni eyi jẹ fun ọ pe o ri ile l'Eko

## Kere o ! Kere o!! Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hannahanna Egbogi gidi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana) pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi kakiri Ilẹ Naijiria

A wa na njẹwọ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni as ko yi ti nwọn fi ṣe ọro ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati o jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o ti wu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni awọn ti tun fi ọwọ sọya tabi pe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun nigbakugba ara wiwo, Ẹsanri ehin didun sisan ati aiko riran kedere ko doro buruku lara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn ba nlo egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile mẹfa abọ (6/6) pere Igo kekere sile mẹta abo (3/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone 22878 (Ọja Ita Faji)

NIGERIAN MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

ATI NI ṢOBU
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA
IBADAN

# ISINKU OLOGBE BILEWU L'ARINRIN

OMUPO Gbogbo ilu lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ kosi gbeji fun ogunlọgọ ọkesimoye awon enia ti o wa sibi ayẹyẹ isinku Ologbe Bilewu ti o jalaisi ni ilu Omupo ekun Igbomina ni ọjọ ojọ.Bọ ti iṣe ọjọ keje osu yi eyiti o fi je wipẹ gbogbo ilu lo nrọ kẹkẹ nigbati Irohin kan kakiri igun mẹrin Naijiria pe Ologbe Bilewu filẹ Ṣaṣọ bora ninu ile rẹ ni Agbo-ile Olomu.

Nigbati awon ọmọ Ologbe na ati awọn ọmọ rẹ ti ri waya gba pe mama ti ku e yara ma bọ nile o ni gbogbo moto ayọkẹlẹ ti nde si ilu Ọmupo lati Offa; E ko Idofia ati awon ilu miran ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria

A bi Ologbe Bilewu ni Agbo-ile kẹta Bilewu ati pe ẹni ọdun mẹtalelogorun (103 years) ni ologbe na iṣe ki o to fi ile aiye silẹ Ologbe na si jẹ ẹniti gbogbo enia mọ ni ilu Omupo ati agbegbe rẹ lori iṣẹ ti o nṣe eyiti iṣe iṣẹ akara dindin.

Ni ọjọ kẹjọ oṣu yi ni nwọn ṣe isinku Ologbe Bilewu ni eto ọna Islam eyiti o si jẹ wipe gbogbo awọn Afa lo jẹ pe nwọn ti bẹrẹsi de si ilu Omupo fun ti ẹyẹ isinku Ologbe na

Gbogbo awọn ọmọ Ologbe na lo si ngna wabiwọsi owo nibi ayẹyẹ isinkun na eyiti o si jẹ wipe nwọn ngna owo bi Ẹlẹda·

Bi awọn ọmọ ologbe na ti ngna owo fun awon enia to wa sibi ayẹyẹ isinku Ologbe Bilewu ni awọn ọmọ Ologbe na tuu fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣe ye ojo na lorun eyiti o fi je pe ọgọrọ enia lo je onje ajeti ni ojo na ti nwon si mu ọti amuti pelu

Bakanna ewe na awon omo Ologbe na tun ngna owo fun awon Alfa jankan jankan ti nwon wa sinku Ologbe na eyiti o je wipe eowo ti awon omo Ologba na fi dupe lowo awon Alfa na je ponun mewa (£10) Isinku Ologbo Bilewu o ko yoyo o si le gongo

Gbogbo awon omo ti Ologbe na fi si ile aiye lo je ogbon (30 children) ati ọpọlọpọ ọmọ ọmọ pẹlu ni nu awon ọmọ Ologbe na ni Ayọka Ayi, Asabi, Lawal, Abudu Ramoni A Bakare ti iṣe oniṣowo pataki ni ilu Eko.

Awa oniwe Irohin Imọle ki gbogbo awon ọmọ Ologbe na pe ki nwọn ku ina wo Oluwa yio gbe Ologbe na si afefe rere amin

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Iwọ yio ri irohin kan gbọ loni tabi ki o ri ohun ti yio da ọ lara ya ti yio mu inu rẹ dun ti iwọ yio si ma yọ,

FISCES (Feb 21 Mar 20) Idamu diẹ yio kọlu ọ ni owurọ oni ṣugbọn nigbati o ba ṣe ara rẹ yio si ya ayọ ati idunnu yio si jẹ tirẹ, iwọ yio si ma tẹ siwaju.

ARUIES (Mar 21 April 20) Iwọ yio pade alatako kan oni; nṣe ni o fi suru ṣee ki o si pana ibanujẹ rẹ nitori ọpọ ire lo mbẹ lẹhin rẹ ki o si toju alafia ara rẹ,

TAURUS (April 21 May 20) Ohun pataki kan yio ṣẹlẹ si ọ loni ki o si fi ọpẹ pupọ fun iwa suru ti Ọlọrun fun ọ dajudaju igbẹhin rẹ yio suwọn ṣugbọn ki o fi suru ati iwa jẹ ma ba awọn enia ti o wa yi ọ gbe,

GEMINI (May 21 June 21) Ibinuati ikanra ni Iwọ yio ji si ni owurọ yi Dupẹ lọwọ ori rẹ ti yio gbe ọ pade awọn enia pataki ati olorire enia loni

CANCER (Jun22 July 22) Odabi ẹnipe otutu fẹ mu ọ diẹ loni maṣe fi ọkan si ala ti la ṣugbon ki o tẹramọ iṣẹ rẹ ki o si foriti nitori eyi ko nse ere Iwọ o si gbọ irohin aladun

LEO (July 23 Aug 22) Ọjọ oni dara fun ọ lati ma lọ se abẹwo kakiri tabi lati na ẹsẹ kiri nitoripe Ire ni iwọ yio ma ba pade nibi kibi ti o ba de ati larin awon obinrin

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Bi o ba ni ẹmi Idarijin diẹ iwọ yio bori gbogbo iṣoro ti o wa ni iwaju ṣugbọn ni pataki ju ki o tọju alafia ara rẹ.

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Ire ọpọlọpọ si mbẹ niwaju ṣugbọn ki o maṣe binu ma si ṣe kanra alafia mbẹ fun ọ pupọ Aworan yiya dara fun ọ lọpọlọpọ

SCRPIO (Oct 24 Nov 22 Ire si mbẹ lọwọ rẹ ti o nse lọwọlowo eyi ni yio jẹki o ni ilosiwaju gidigidi

SAGTTARIUS (Nov 23 Dec 21) Are yio mu o lowuro oni ṣugbon nigbati osan ba pon idẹra yio dara ki o lo ṣe abewo awon ore re

CAPRICON (Dec 22 Jan 21) Ọjo oni yio dara fun o ṣugbon maṣe fi ara sile fun are dubule ki o si sun eyi daraju,


# O Ti De Jaburata

Eyi ni lati kede fun awon Onibara wa pe. Iwe Itumo Ala. Iṣẹ Wiwo, Ọjo Ibi Ọmo de ati Oogun Ajebidan alapapo wa nilẹ fun tita nisisiyi, tete wa ra tirẹ loni ki o to tan.

A si tun ṣẹṣẹ ṣe iwe Itumo Ala miran lati owo Joseph Alala

Irohin ko to afojuba 3/6d pere ni ẹyo kan, mejila tabi dosinni rẹ jẹ 30/-

J. O. SHOYINKA
P. O. Box 159,
tabi 9, Iyala Street,
Mushin.

A si nfẹ awon ti yio ma ba wa ta awon iwe wa na

Tete wa si ọdọ Olotu



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

POPULAR PRINTING PRESS
9, Iyala Street, Mushin,



E Ma Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

# Ero Mi Lori Ọrọ Ibiam ati Kotoye

## Lati Oju Ewe Keji

lonakona ti eda le ba ara won ja n. aja bori

12 Lọna kejila Dr. Ib'am wipe lotitọ ati lododo awa ko tan ẹnikankan je bi ko se ara wa n.wọn bi awa ba ntanju ohun ti aiye yi ti awa ko wa ohun ti emi ti igbagbo eyiti iṣe ipinfunni ninu ifẹ ara ki asi tele ohunti isẹ ti iwa irẹlẹ iwa aimọtiara ẹni nikan papa gidi Dr Ibiam fi ẹnu ba pe ẹkọ ti awi pe aniko duro lori iwarẹle ako ni iberu Ọlọrun ninu ọkan wa eti pe awa ko tera mọ ohun ti ṣe ti ibile wa gegebi orile ede Onl ju gbo gbo awon iwa wonyi awa fe ohun adamo ti ko mu ro awa buru ninu ise ati iwa wa Dr nl a ni atl se gafara fun iwa buburu gbogbo ki a to di orile ede pipe Ododo ni awon oro n wọyi bakanna

13 Lọna kẹtala Dr Ibiam ni o dabi ẹnipe awa gbagbo po ilẹ Naijiria jẹ ti gbo gbo wa pọ, Nitoripe awon baba wa lo ni ti wọn si bi wa sinu ilẹ na, bakanna awa na yio tun fi silẹ fun awọn ọmọ wa lẹhin ọla titi lati irande i an, A si lati ranti pe awa alaye to wa loni ni o ni lati tun ile wa ṣe titi a o fi silẹ fun awọn ẹlomiran, Ti a ba pin ara wa niya lai ni ironu pa ọkan ni wa dijudiju ani lati ṣubu ninu aimo wa titi awa ki o si mọ. Ohun to wa fun ẹnikọkan nipa ki a ri pe a tun ile ati ẹna wa ṣe dada Dr Ibram ran wa leti wipe iwa ki a ma ya ara wa nipa pe ẹya bayi ni ẹnikan si ẹnikan jẹ ohun ti o fẹrẹ ba iwa ibagbọ wa jẹ Bakanna ni Iwa Ẹgbẹ oṣelu gbogbo ti fẹrẹ ba ile wa jẹ O ni ọpo ninu awọn ti o nṣe ilu ni ko mọ riri nkan ti wọn nṣe loni yi Nitori pe ẹnikẹni ti o ba nṣe ilu na lati mọ wipe anfani fun gbogbo ara ilu ni on wa fun ju pe ki a ma yan ara wa lodi ki a si ma le ara wa ka kiri ilu Dr Ibiam so pe iba dara papọ ki olukaluku mọ ohun ti eto sişe jade dada ki won to bẹrẹ si pariwo kiri lasan

14, Lọna kẹrinla Dr. Ibiam sọ pe nigbati pupọ ni ija ati ikolu ma wa larin awọn oṣelu wa fun iwa imọti ara ẹni. O ni ti o ba jẹ pe a ni ẹkọ to yẹ kọrọ lori ilu şişe ni a o fun ara wa laye lati lori eto ilu şişe yi. Nitori pe gbogbo wa ko le wa ni ipo giga lẹkan ṣoṣo. Fun idi eyi o ye ki a mọ pe ire ati ilọsiwaju ilẹ wa ni eto oṣelu wa fun. O ni ọpọ wa fun işẹ abẹle tl yio mu ire ati idagbasoke wa ba ile ju igba ti o wa nipo oṣelu, şugbọn ti awọn mejeji bo ti uja fun ipo yi alafia ko ni si mọ lati ronu lori awọn nkan to dara lati şe.

15 Lọna karundinlogun Dr. Ibiam fiye ni pe ọna kan wa ti awọn oşelu wa tẹlẹ ti ko dara rara, Eyini nigbati iruju kan ba wa larin ilẹ wa yi ọpọ ninu awọn oşelu wa ti nwọn iba jade lati pana rẹ, Dipo ti nwọn iba şe nwọn yio wa joko ma woran bi alainani nipa ọrọ na, O ni iru iwa yi ko mu ọgbọn dani bikoşe ojo, O ni ọna pupọ lo wa ti a le pana irukerudo larin wa laipariwo, Mo ro pe ọrọ yi dara pupọ nitori kekere ri ati pa şe irako bi o ba dagba tan owo ko ni ka ni awọn agbalagba nwi fun wa.

16. Lọna kẹrindinlogun Dr, Ibiam ran wa leti awọn enia nlanla ti o ti kọja bi ogunna gbongbo kan ni Rosia Czar ti Rosia Napoleon Bonaparte, Hitler ti Germani ati awọn ẹni nlanla bawọnni tinwọn ti kọja lọ ti iran ti fẹre di ti igbagbe. Nitorina o fi ye wa pe ki a şe oju şe wa nigbati a ba wa ni ipo rere. Nitoripe ẹjọ kan nbọ wa ti awọn to nii aiye loni ki yio le mi koriko kan lẹhin ọla. Nitorina ẹ jẹki a ro awọn ọrọ yi.

17. Lọna kẹtadinlogun Dr. Ibiam mu wa si iranti wa awọn ọmọ ilẹ wa ti o wa ni ipo ihamọ kiri fun aşişe kan tabi keji. O ni awọn ẹlomiran ninu wọn ẹjọ ni mimọ. O ni ti ki ba şe ohunti iwa oşelu mu wa si arin wa loni iru awọn to sare kiri fun aşişe wonyi, nwọn ki ni ohun pataki ti nwon ni lati ma şe fun idagbasoke ilẹ wa yi. Dr Ibiam sọ pe o yẹ gbogbo enia ti o wa ni ipo ọla loni wa ni işọra pupọ nitori ko si ẹnikan ti o mọ ẹhin ọla

18 Lọna kejdinlogun Dr biam ni ki gbogbo awọn ti o wa ni ipo ọla ninu Ijoba lọ şọra pupọ ni ẹna ti awa ni ipo ọla wa tabi ọwọ ati oro wa lati ma te awọn ẹlomiran mọlẹ ni ọna ti ko tọ rara. O ni ẹnikẹni ti o ba nwa ọna işubu awọn ẹlomiran tabi ni pataki ilẹ wa, O ni o daju Oluwa ẹlẹsan ati olupin funni yio pin ohun rere fun awọn ti o tọ si

19 Lọna kọkandinlogun Dr Ibiam fi ọrọ Ọlọrun jẹ omitoro pe ẹnikẹni ti a ba ba wi ti o wa ọrun ki yio parẹ laisi atunşe, Nitorina o yẹ ki gbogbh wa gbọ ibawi ati ikilo to tọna rere

20 Lọna ogun Dr, Ibiam sọ pe on koro ara on ju bi oti yẹ lọ ati pe ko yẹ ki ẹni kan ro ara rẹ jubi oti yẹ lọ Nitorina ohun kohun ti on ba se fun işẹ Ọlorunari fun ijọba on ore ọfẹ Ọlọrun niyẹ Ko si ohunti awa ti a wa lori le şẹ ti awọn ọmọ wa ko lese jubẹ lọ lẹhinọla

21 Lọna kọkanlelogun Dr. Ibiam na ọwọ ẹbẹ si orişirişi awọn wọnyi. si gbogbo awọn Governors ti o wa ni ile yi, Olotu Ijọba Apapọ, (Prime Minister) Awọn Olotu Ẹkun Ile wa (Premiers) Gbogbo awọn Oloye Aḃọba şapero (Minister) Awọn oşelu gbogbo (Politicians) Awọn Oşişẹ Ijọba nla ati kekere Civil servants) Bakana ni gbogbo awọn obinrin ile wa ki wọn pa ero nwọn pọ lati şişẹ fun ilọsiwaju ilẹ wa Naijiria,

Bayi ni Dr Ibram fi adura pari gbogbo ọrọ rẹ pe:-

Ki Ọlọrun bukun Ilẹ Naijiria ti a fẹ,

Ki Oluwa şe amọna awọn aşaju rẹ, ki o tan ju awọn enia ile yi.

Ki o si fun wa ni alafia nigbati wa,

Ẹ o tun ma ka ọrọ ti Ọgbẹni N, A, Kotoyẹ lola

O di gba,


# O Ti De Jaburata

Eyi ni lati kede fun awon Onibara wa pe. Iwe Itumo Ala. Işe Wiwo, Ojo Ibi Ọmo de ati Oogun Ajẹbidan alapapo wa nilẹ fun tita nisisiyi, tete wa ra tirẹ loni ki o to tan.

A si tun şeşẹ şe iwe Itumo Ala miran lati owo Joseph Alala

Irohin ko to afojuba 3/6d pere ni ẹyo kan, mejila tabi dosin ni rẹ jẹ 30/-

J. O. SHOYINKA
P. O. Box 159,
tabi 9 Iyala Street,
Mushin.

A si nfẹ awon ti yio ma ba wa ta awon iwe wa na



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

Tete wa si ọdo Olotu

POPULAR PRINTING PRESS
9, Iyala Street, Mushin,

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No. 1,492 TUES DAY OCTOHIF 26, 1565 (2D


## Aara San Pa Ọmọ Ile Ẹko Kan

KAFANCHAN:- Jinnijinni dabo gbogbo enia ariwo gba gbogbo adugbo kan nigbati aara san pa ọmọ ile ẹkọ kan ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdogbọn oṣu yi ni ilu Kafancha Ipinlẹ Ariwa ile Naijiria nigbati ọmọ ile ẹkọ na npada bọ wa sile lati ilẹ ẹkọ wọn ni ọsan ọjọ na eyiti ojo nla kan bẹrẹsi rọ ti o si fa sisan aara na lọwọ.

Irohin tun fi ye wa pe aara to san na tun pa awọn ọmọ Akẹkọ ti ile ẹkọ giga ti Kafanchan Secondary School lara eyiti o jẹ wipe lẹsẹkẹsẹ ti aara na san ni awọn ọmọ Akẹkọ na si ṣubu lulẹ ti nwọn si daku fun Ọpọlọpọ iṣẹju ki nwọn to le tun pada saiye.

Oniwe Irohin wa tun fi ye wa pe ki iṣe nibi kanna ni iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ ni ilu Kafanchan ati pe ibiti aara ti san pa ọmọ ile ẹkọ ti o ku na jẹ ibi to yatọ si ibiti awọn ọmọ ile ẹkọ mẹfa ti fara gbọgbẹ ninu aara nla to san na.

Nwọn si ti gbe awọn Akẹkọ mẹfa to fara pa ninu aara to san na lọ si ile Iwosan lati lọ ṣe itọju wọn.

# ENIA MẸFA M'ORIBỌ NINU ẸJỌ IDANASUNLE

IBADAN:— Idunnu ṣubu lu ayọ ti ayọ si ṣubu lu oyin ni ọjọ Ẹti ti iṣe ojọ kejilelogun oṣu yi fun awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA mẹfa ti nwọn jare ejọ ti awọn Ọlọpa nba awọn ọdaran na ṣe pe, nwọn dana sun ile asiwaju ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ kan ti o njẹ Ọgbẹni A Akande Gbadebọ ti nwọn tun ba mọto rẹ jẹ ni ọjọ kẹtadinlogun oṣu keje ọdun ti o kọja.

Awọn enia na ni Ọgbẹni Surday Michael Afọlabi, ti o jẹ Asiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre ni agbegbe Ọshun ṣugbọn Moses Ajayi, Layinka Adio, Samuel Ọshọkọya ati Peter Osawere ni nwọn jẹbi ẹsun mẹta ninu marun ti awọn Ọlọpa mu wọn fun ti nwọn si lọ si ẹwọn lori ẹsun ti Ọlọpa ka si wọn lẹsẹ.

Ile ẹjọ giga ti Ibadan ni Layiwọla Adio jẹbi ẹsun karun lori pe o hu iwa ti o le ba alafia ilu jẹ. adajọ ni ki o fi ọwọ si iwe lori adọta pọnun ati onigbọwọ kan pe on yio maa hu iwa rere fun odidi ọdun kan.

Moses Ajayi jẹbi ẹsun kẹta, ẹkẹrin ati ẹkarun nitorina ki o lọ si ẹwọn oṣu mẹta, oṣu mejila ati oṣu kan lori awọn ẹsun na, ki o lo gbogbo rẹ papo a jẹ wipe oṣu mejila pere ni yio lo lọgba ẹwọn.

Samuel Ọshọkọya ẹniti gbogbo enia mọ ni (Redionic) si jẹbi ẹsun kẹta, ẹkẹrin ati karun, idajọ tirẹ ni lori ẹsun kẹta ati ẹkẹrin ki o lọ si ẹwọn oṣu mejidinlogun pẹlu iṣẹ aṣekara lori ẹsun karun ki o lọ si ẹwọn oṣu kan.

Peter Osawere jẹbi ẹsun kẹta, ẹkẹrin ati ẹkarun, o o gba idajọ ẹwọn oṣu meji la pẹlu iṣẹ asekara lori ẹsun kẹta ati ẹkẹrin ti o si gba idajọ oṣu kan lori ẹsun karun pẹlu iṣẹ asekara.

Nwọn yio lo gbogbo ẹwọn na ni apapọ tabi ẹwọn ti oṣu rẹ ba gajulọ ni nwọn yio lọ.

Awọn enia mejileloeun ni nwọn kowa siwaju adajọ agba ni Ibadan, adajọ fi mej la silẹ ninu wọn nigba ti agbẹjọro wọn fun ile ẹjọ na pe, awọn ọdaran na ko ni ẹjọ lati ro.

Ninu Idajọ ti adajọ na da ni o ti sọ pe on ko gba ọrọ ti awọn ọdaran na so lati gba ara wọn sile gbọ pe ọgbẹni Gbodebọ ni o kọkọ yinbọn lu awọn.

## Dọkita Dike Binu Si Iwa Awọn Ọlọpa

IBADAN:- Inu bi olari ile ẹkọ giga Yunifasiti ti Ibadan ọjọgbọn K O Dike, lori iwa ti awọn ọlọpa hu si awọn akẹkọ nigbati nwọn fi to lọwọwọ kakiri inu ọgba wọn pe, awọn lodi si abayori ibo ti nwọn di ni Ipinlẹ Iwọ Orun ti awọn ọlọpa bẹrẹsi fi kondo dara si awọn akẹkọ na lara o tun ka awọn ọlọpa lara, nwọn nwọle tọ awọn akẹkọ ni yara wọn, ti nwọn da ọgbẹ si akẹkọ lara ti nwọn si ba gbogbo dukia awọn ọmọ ile ẹkọ na jẹ.

Nibi ipade awọn oniwe irohin ti ọjọgbọn Dike, pe ni opin ọsẹ to kọja yi ni o ti sọ fun awọn oniwe irohin pe, on ti mu ẹsun awọn ọlọpa lọ sibiti o ga julo lo ri iwa ti nwon hu si awon omo ile ẹko on.

Eyi ni ẹkunrẹrẹ ọrọ ti o so:—

"Lati igb ti mo ti de lati Eko, m ti fi gbogbo ara gbọ nipa iwa ti awọn Ọlọpa hu ninu ọgba awọn akẹkọ ati bi nwọn ti di ọgbẹ si awọn eni i enia lara pẹlu ọpọlọpọ ohun ini ti nwọn bajẹ ni ọjọ kẹrinla osu kẹwa ninu odun yi.

"Mo ti gbọ ninu ẹrọ asọromagbesi mo si tun ti ka ninu iwe Irohin meji kan ti o jade ni ọjọ Aiku (Times and Post) pe, awọn ọmọ ile ẹko na ti gba iwe ihamo sinu ogba won fun igbo kan na.

"Mo fẹ ki o han gbangba si gbogbo enia pe mo ti lo fi oro na han awon alaṣẹ ti o ga julo lori iwa ibajẹ ti awon Ọlopa hu ni ojo na.

LAIGBAṢẸ

Mo lẹ tun so pe ore to jade lati inu ile iṣẹ ẹro Redio at irohin ti iwe meji i ko ni kẹrindinlogun at ẹ ẹ tadinlogun oṣu kẹwa odun yi ti si enia lona patapata ati pe adele oga ile eko giga na ko fun ẹnikankan la ṣẹ lati soro lori iwa ti awon omo ile ẹko na hu ati pe ko si ẹni ti o soro fun ẹnikan kan lati tẹ jade ninu iwe ta bi so jade ninu ẹro Redio.

Igbimo to ndele de mi la siko pajawiri ko ran eniti o ni iru oro to jade yi, mo si tun nṣe iwadi ibiti oro na ti jade wa, nitoripe ko si ẹniti o fun ẹnikan laṣẹ sọ iru oro bẹ sita.

Ọrọ ti o jade lati ọdọ awọn ọmọ ile ẹkọ giga ti Ile-Ifẹ ati ti Ibadan ni pe ni ọjọ kẹrinla oṣu yi awọn yoi ṣe eto ipade iwọde yi Ibadan ka lati fi ẹdun ọkan awọn han pe, awọn lodi si abajade ibo ti nwọn ci koja eyiti abayọri ibo na jẹ yan jija larin ẹgbẹ Oṣelu mejeji,

Ẹgbẹ Itẹsi-aju nlogun pe, omo ẹgbẹ awon ni o bo ri ninu ibo ti nwon di koja paapa awon wole jaburata.

Igbimo ti o nmojuto ibo didi ni Ipinlẹ Iwo Orun so wipe, ẹgbẹ Dẹmo ni o wole julo ninu ibo na eyiti o fa ti awon enia nfi ilodi won han nipa eyiti awon ẹgbẹ akẹko na je okan ninu won.

Ṣugbon irohin kan lati Unifasiti ti Ibadan so pe bi awon akẹko na ti nmura lati bẹrẹ iwode na ni oko awon Ọlọpa Eko ati ti Ibi lẹ bade ti nwon bẹrẹsi lu awon akẹko.

Ninu ariyanjiyan yi ni awon Ọlopa ti na nwon ni Inakuna ti awon miran si fi ara gbogbẹ, eyiti o burn nibẹ ni pe, tulasi ni awon akẹko fi lo ha arawon mo nigbati owo Ọlopa tẹ diẹ ninu won.

owo oṣu ti awọn na bi nwọn ko ba da ẹkunwo ow oṣu ti nwọn duro

Ninu ti awon ọmọ ẹgbẹ okawe ti Unifasiti sọ ni nwon ti ṣe alaye pe, ẹkunwo ti awon omo ẹgbẹ Igbimo Aṣofin Apapo ṣe fun arawon ba nkan jẹ papo kosi ninu omo ilẹ Naijiria ti inu re dun si oro na.


Printed & Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Stree t, Lagos. Phone 21915
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street L agos. 26/10/65